**Ọrọ agba**

ỌPẸKẸKẸTẸ ndagba, iru adamọ mbajẹ. Otitọ d'ọ'a o kuta, owo lowo la nreke; otitọ ni bori irọ nikẹhin.

# Irohin Yoruba

**Akiyesi**

POLOWO ọja rẹ ninu iwe 'Irohin Yoruba' Oloyinmọmọ ti o nta ni ọja bi akara gbigbona.

NO. 116 WEDNESDAY JULY 8 – TUESDAY JULY 14 1964 KOBO MẸTA 3D

# IRAN YORUBA BỌ SINU OKUNKUN

## Ọrọ Olotu

### RIKIṢI PIN!

KO le sai ya awọn onilaakaye enia lẹnu pe awọn ọdalẹ le ma yọ nigbati alagbara ba 'nṣubu'. Ohun ti o le mu idunnu awọn aṣiwaju ẹgbẹ Dọmọnu wa nitoripe nwọn gbe Oloye Obafẹmi Awolọwọ sẹwọn ko iti ye wa. A gba pe orogun oselu ni nwọn jẹ si Oloye Awolọwọ ṣugbọn iyẹn ko sọ wipe bi nwọn yan digbolugi ati onirikiṣi enia to, ẹjẹ enia ko si ni ara wọn mọ. Ki iha ṣe otitọ nipe bi a ba nge igi ninu igbo, a fi wọn ara eni wo?

OHUN ti o ye ki o pa awọn aṣiwaju ẹgbẹ Dọmọnu lẹkun lo npa wọn lẹrin. Ipa ti Ọnabamiro, Ogundiran ati Ọshuntokun ko ninu ọrọ na o se ajeji si ẹnikẹni. Igba ko lọ bi rere, oni ni a ri, Yarabi lo mọ ọla. Ijiya ti Oloye Awolọwọ lo de loni, tani mọ ẹniti yio kan lọla? Gbogbo rikisi ti ẹgbẹ awọn ọdalẹ di pẹlu ẹgbẹ Alaake lati fi iya jẹ awọn ọmọ Yoruba ndopin lọ. Rikiṣi pin alagbẹdẹ ko ri beba rẹ.

ORI ẹiyẹ ni ko pa ẹiyẹ. Ki iṣe ifẹ inu awọn aṣiwaju ẹgbẹ Dọmọnu pe Oloye Awolọwọ nmi loni. Iru iya wo lo tun wuwo fun ọmọ ẹda ju eyiti ỌGAGUN awọn Yoruba farada? Yatọ si pe o wa lọgba ẹwọn, akọbi rẹ ku mọ loju. Lori gbogbo wọnyi, ẹgbẹ Dọmọnu tun ro wipe o yẹ ki awọn fi Oloye Awolọwọ rẹrin.

KI iṣe Oloye Awolọwọ ni iru idamu aiye bayi kọkọ de si. Lẹhin ti Judasi ti fi ọga rẹ, Jesu han, ti o si di rikiṣi pọ pẹlu awọn ALASẸ igbani, awọn kan Jesu mọ agbelebu. Orukọ Jesu di wura iyebiye loni nigbati orukọ Judasi parẹ. Ẹwọn ọdun mẹjọ ni awọn alaṣẹ fi Alagba Jomo Kenyatta ti ilẹ Kenya si ṣugbọn nwọn tun bẹ jade ninu ọgba ẹwọn na ni lati wa di Olotu Ijọba ilẹ Kenya olominira. Inu ọgba ni nwọn ti fa Dokita Kwame Nkrumah jade wa lati di Olotu Ijọba ilẹ Ghana.

A gba pe ikoko ti yio ba jẹ ata, idi rẹ gbọdọ gbona. Aṣiwaju gbọdọ j'ya bi aṣiwaju 'ilẹ Mimọ' ti Jomo Kenyatta, Dokita Kwame Nkrumah, Pandit Nehru (ni igba aiye rẹ) lọ lati di aṣiwaju ilẹ wọn ni Oloye Awolọwọ lọ. Awolọwọ lọ si Mẹkka oṣelu lati gba

Wo oju ewe kejọ



ATỌKA

Alapara Ibadan: Oju ewe keji

Kini ojo iwaju awon oba? Oju ewe keji

Atako lori idajo Awon: Oju ewe kerin ati ikarun

Kobiowu Joba: Oju ewe kejo

OLOYE ỌBAFẸMI AWOLỌWỌ

Gbogbo ẹgbẹ oselu ti o wa ni Ipinlẹ Iwo-Orun, yatọ si ẹgbẹ Akintọla, ni nwọn ti kọ ipinnu ile ẹjọ ganran ni Eko ninu eyi ti nwon gbọn ẹjọ kotẹmilọrun ti Oloye Awolọwọ pe sọnu ni ọjọ kini osu keje ọdun yi.

Ile ẹjọ na ti sọ pe awon faramọ Idajọ G. S. Ṣowemimo ti odun ti o kọja ninu eyi ti o ju Oloye Awolowo si ẹwon ọdun mẹwa.

Awon meta ninu awon ti o pe ẹjọ kotemilọrun na ti ile ẹjọ da silẹ-awon ni Adeyiga Akinsanya, Ayo Akinsanya ati Morison Okotie-Yesin.

Ọkan ninu awon adajọ na ti ṣe adajọ agba fun Ipinlẹ Ila-Orun, ti o tun jẹ ọkan ninu awon adajọ marun ti o gbọ ẹjo na, Ọlọla Louis Mbanefo sọ wipe on ko faramọ ipinnu ile ẹjọ nipa ti Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ lori ẹsun kini ti nwon fi da ẹwon ọdun mẹwa fun.

Adajọ na Ọlọla Mbanefo sọ wipe ọdaran ni Dokita Ọnabamiro ti o jẹri pe on wa ninu Igbimọ Elero (Tactical Committee) ẹgbẹ Afẹnifẹre ati pe ẹri rẹ koyẹ ki o mu ina d'oko nitoripe ko si ẹlẹri miran ti o gbe ẹri rẹ lẹsẹ

Ninu ikede ti ẹgbẹ Afẹnifẹre gbe jade ni kete ti ile ẹjọ parí idajọ rẹ lori Olo-

(Wo oju ewe kejo)

## Ọwọ Taylor tẹ ẹ

ỌLỌLA J.I.C Taylor, okan ninu awon adajọ ile ejo ganran marun ti o so Oloye Ọbafẹmi Awolowo, babasale egbe Afenifere Naijiria si ewon odun mewa pelu awon mesan miran ti di adajo agba ile ejo giga Eko ni ojẹ keji ti nwon se idajo Oloye Awolowo ti ise ojo keji osu keje odun yi.

**Gbadun Ẹmi ẹ pẹlu STAR**




Ọti Beer to gbamuse!

